Iwo ki yio fi o'tan mi silẹ ni ipo-oku beni; bẹni Iwọ ki yio jẹ ki Ẹni Mimọ Rẹ ki o ri idibajẹ.

# Irohin Yoruba

VOL. IX No 458 MONDAY APRIL 19, 1954 KOBO KAN (1d)

E ma a polowo oja nyin sinu iwe Irohin Yoruba

## Obirin Kan Jinde Kuro Ninu Oku

MỌLAI-MAJDUGURI- Iyalẹnu ati ibẹru kekere kọ ni o jẹ nigbati awọn ti o wa ni abulẹ Mọlai ti o jinna ni busọ marun si Maiduguri ri obirin ara ileto wọn ni arin ọja, eniti o ti ku ti nwọn si ti sin ni ọdun kẹta sẹhin.

Obirin (Oku) na ro asọ ọgbọ funfun ti ilepa ti sọ di balabala, o si sọ fun awọn ara ileto na ti nwọn ngbọn fun ibẹru pe oku ni awọn ri yi! pe ki nwọn fi ọkan balẹ, on ba iṣẹ pataki wa lati jẹ fun Malamu Abusi Balẹ abule awọn na ni.

Iṣẹ na si jẹ mọ ti Ẹmi Ajinde, o si sọ fun Balẹ abule na pe awọn olugbe abulẹ na kun fun iwa ibajẹ-ọdọdo lọpọlọpọ gbogbo nwọn ti a ba yọ owọ ẹnikan ṣoṣo ninu wọn ni o ti da ẹṣẹ ti o buruju, nwọn si ni lati ronupiwada.

Nwọn ko si ri obirin (oku) na mọ, bi o ti jiṣẹ na tan ti o si fi ọwọ kan Malamu Kari l'ori ẹnikan ṣoṣo nati o sọ pe o nṣe ododo ni o ba poora.

Obirin (oku) na si tun fi ara han ni ọja ki o to lọ patapata, o si tun sọ inkan kanna ti o ba Balẹ Abule wọn sọ p. nwọn ti dẹṣẹ buburu ki nwọn ronupiwada.

Nwọn ko ri obirin [Oku] ni mọ, sugbọn ọrọ rẹ ko tan nilẹ ti awọn enia si nbi ara wọn lere pe iru kini eyi jẹ ni Aṣeko Ajinde. Nitori inkan yi ṣelẹ nigbati Ọdun Ajinde. Ọdunni ti a nṣe lọwọ-lọwọ ku ọjọ marun ni.

## Ijoba Yio Ko Igba Ile-Iwe f'Abekuta

ABẸOKUTA -- Lati ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu ti o kọja yi ni Ọlọla J. F. Ọdunjọ (Minister for Lands) ti Ijọba Iwọ-orun Nigeria ṣe aṣiwaju awọn Igbimọ Alatunṣe Ilu (Regional Advisory Planning Committee) lọ si ilu ati ileto gbogbo ti o wa ni Ẹkun Abẹokuta lati mọ ibiti o tọ ti o si yẹ fun kikọ awọn ile-iwe si ati bi nwọn yio ti ṣe kọ wọn. Gbogbo awọn ile-iwe ti nwọn nfẹ kọ na jẹ igba (200.)

Ajọ Igbimọ ti o rinrin ajo na "Abẹokuta Divisional Committee" ṣe ipade ni ọjọ Ajẹ ti iṣe ọjọ kejilelogun oṣu ti o kọja na, nwọn si ba awọn Igbimọ Lori Ẹkọ ṣe ipade pẹlu ni ọjọ kerinlelogun oṣu na. Ni ọjọ kẹtadinlogbọn oṣu kanna ni Ọlọla Igbimọ na ba Igbimọ Ẹkọ Ẹgbado (Ẹgbado Education Committee) ṣe aṣaro lori Ẹkọ.

## Alhaji Kesington Sin Omo F'Oko

EKO- Ni ọjọ Aik : ti iṣe ọjọ kejidinlogun oṣu ti o kọja yi ni Alhaji A. A. Kesington Balogun Janma Alalukurani sin ọmọ rẹ bẹwaji obirin Amudatu Amọkẹ Ọmọlara Kesington fun ọkọ rẹ Ọgbẹni Abudu Razaki Ajala Davies ni gbọngan apejọ awọn ọmọ ile-iwe Ansar-Ud-Deen (Alakoro.) Alfa M. K. Ekemọde ni o ṣe isin igbeyawo na.

Bi nwọn ti so yigi tan ni baba iyawo na ba ti bẹrẹsi fi oriṣiriṣi onjẹ adidun tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun, ni gbọgan apejọ Tom Jones.

Iyawo na dun o larinrin, irohin ko to amojuba ni.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ijoye Elelu Edibo, Ọbanikoro, Modilẹ, Olumẹgbọn-Ajaiye, Onis wo, Aromirẹ, Erelu, Faji, awọn Alihaji Solomon

Wo oju ewe kẹrin



Eyi ni aworan iranti ti Gomina ya pẹlu Adajọ Agba Nigeria Ọlọla John Verity. Gomina ati Iyawo rẹ ni o wa ni ọwọ osi, Adajọ Agba na pẹlu Iyawo rẹ ni o wa ni Apa ọtun.

## Moto Pa Akeredolu-Ale

EKO- Ni oru ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kọkanla oṣu yi ni iṣẹlẹ ibanujẹ ṣẹlẹ pe moto ṣe ijamba o si pa Ọlọla Oladipọ Akeredolu-Ale nigbati o di eni ọdun mọkanlelogoji laiye. Bi o ti nwa moto rẹ bọ l ti Eko ti o de Ilet Sogunlẹ nigbati o npada lọ si Ikeja ni mọ.o rẹ na jin si koto ni o ba fi ku.

Ọmọ Ondo ni i, ile-iwe Methodist Boys' High School, Eko ni o gbe ti kọ iwe, on ni ẹniti o da Ẹgbẹ awọn Agbẹ "Nigeria Farmers' Union" silẹ ni 1939. Ẹgbẹ na si ti ni to adọjọ (150) ẹka nisisiyi on ni akọwe ati alafẹhinti Ẹgbẹ na nipa iṣẹ ribiribi ti o nṣe fun ilọsiwaju rẹ ati akinkanju ti o ni.

Nitori ki Ẹgbẹ na ba ni ilọsiwaju ni o fi rinrin ajo lọ si Germany lẹmeji ati Belgium, fun ọpọlọpọ igba ni o si fi



Ologbe Akeredolu-Ale

npara ilu Gẹẹsi. Aṣiwaju ẹka Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) ti Agege ni o jẹ ni igba aiye rẹ. Ninu Ẹgbẹ Afẹnifẹre na ni o gba jẹ ọkan ninu awọn Aṣoju Igbimọ Aṣofin Ijọba Iwọ orun ati ti Igbimọ-Nla Aṣofin Nigeria. O fi baba rẹ ti o ti darugbo ati awọn ọmọ mẹjọ si aiye lọ.

Oloye J.A. Ogunji Olu Agege ati adajọ Agba Kotu Ijọba Ibilẹ Ikeja sọ pe oro ni iku Ọgbẹni Akeredolu-Ale jẹ fun gbogbo ara Ikeja paapa fun ara Agege. Emi ko mọ ọna wo ni a le gbagba ti a o fi daruko rẹ lairanti iṣẹ ribiribi ti o ṣe fun Ẹgbẹ awọn Agbẹ "Nigerian Farmers' Union" ti o fi lakaye ati agbara rẹ dasilẹ Aṣeko ti o yẹ gan an fun lati mu eto rẹ ti o ti ṣe silẹ lo niyi. Nigbati mo ri gbẹhin o wọ pẹlu alafia, emi ko si ro pe arimọ ẹmi pẹlu rẹ niyẹn.

Ọgbẹni J. A. Akerele ọkan ninu awọn Igbimọ Ilu Agege [Agege Town Council] ẹniti o sunmọ ologbe na pẹkipẹki sọ pe "Emi koiti ri ẹniti awọn ara ilu rẹ fẹran bi ologbe na. Iku rẹ jẹ ibanujẹ gan an fun "Ẹgbẹ Farmers' Union." Awọn enia pataki pataki ati awọn Ẹgbẹ Afẹnifẹre pẹlu awọn ogunlọgọ enia ti nwọn lọ sin in ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu kanna ni Agege. Enia dabi omi nibi isinku na, ẹni jẹ orihun nsunkun ni, irohin ko to amojuba.

### Kristi Ji Dide Kuro Ninu Oku O Si Di Akobi Ninu Awon Ti O Sun

PR-GRESS

O! ARE U MISSING

16 hours of it for less than

3D A DAY---GET REDIFF-SION

Aworan yi ni ti Ọlọla Bonfils ti i ṣe Gomina Dahomey ati Iyawo rẹ nigbati nwọn nwọ Afin Alake lọ ni Abẹokuta, Alaiyeluwa Ad mọla Kej[i] Alake Abẹokuta pẹlu awọn Ọba Abẹokuta yoku ati awọn ẹmẹwa rẹ si gba Gomina na ati Iyawo rẹ ni alejo tọwọ-tẹsẹ.



## Ile-Iwe Ofe Ni 1955

Lati oju ewe kẹta

muwa, yio jẹ ẹri pataki nipa ọjọ-ori ọmọ na.

OMỌ GBỌDỌ LỌ SIBẸ

Awọn obi tabi alagbatọ nilati mọ pe "a ki fa ori lẹhin olori" nwọn ko gbọdọ fi ọmọ sẹhin nigbati nwọn ba nlọ forukọ rẹ sinu iwe. Afi bi Igbimọ Eleto Agbegbe wọn ba gba a fun wọn, awọn ọmọ gbọdọ tẹle awọn obi tabi alagbatọ wọn lọ sibẹ.

ILE-IWE GBỌDỌ SUNMỌ ADUGBO ỌMỌ

Awọn ọmọ nilati forukọ silẹ fun ile-iwe ti ko jinna si ibiti nwọn ngbe ju maili mẹta lọ. Nwọn gbọdọ forukọ silẹ ni ile-iwe kanṣoṣo pere.

IWE IWỌLE.

Ao fun awọn obi tabi alagbatọ ọmọ to ba yẹ ni gbigba si ile-iwe ni iwe iwọle ti ọmọ wọn yio fi wọ ile-iwe, ao si koruko ọmẹ wọn sinu iwe oruko.

(Koi ti pari)

## Kesington F'Omo F'Oko

Lati oju ewe kini

Danmọle, Oshodi, R. Ajala, Lasisi Andoyi, awọn Ọgbẹni Jimọh Aiyepe, A. Rahim Aiyepe, Iyaafin Faumọta Ajiwun Oki, Awọn Oloye Ọtun Balogun Eko, Osi Balogun Eko, Ẹkẹrin Balogun Eko, awọn Ọgbẹni Karimu Kọlun, A. K. Asani [Baba Dudu], Y. Baruwa [Iya Atata], Abudulai Opere, Hadji Abibulai Ibn Disu Labulọ ati Ọgbẹni Amudanu Gaji.

Ki Ọlọrun se iyawo ati ọkọ rẹ ni olori ire, ki O si fi ire kari gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na o.

## *A Ba Olomo Yo*

KOFORIDUA G. C.—Ni ọjọ Iṣẹgun ti ise ọjọ kọkọndilọgbọn oṣu kejila ọdun ti o kọja yi ni Ọlọrun fi ọmọbirin kan ta Ọgbẹni Gbadamọsi Iyanda ati aya rẹ Bintu Ajikẹ lọrẹ. Lati igbati ọjọ isọmọloruko ti ku ọla ni baba ọmọ na ti bẹrẹsi ṣe inawo idawọ titi di ọjọ ikomọ.

Ni dede ago mẹjọ arọ ọjọ ikomọ ni awọn Alufa ati awọn enia pataki pataki wa ṣe suna ọmọ na. Lemọmu Salifu Dandawa ati Alhaji Yusufu Ayinla ni wọn ṣe isin isọmọloruko na, nwọn si sọ ọ ni Sikiratu Latundun Abẹgbe. Lẹhin isọmọloruko ni Alhaji Sunmọnu ẹgbọn iya ọmọ na de lati Accra pẹlu awọn "janma" rẹ.

Baba ọmọ na fi orisirisi onjẹ adidun ati orisirisi ọti ati ọpọlọpọ siga tẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na lọrun. Alhaji Sumọnu ati awọn "janma" rẹ ati Ọgbẹni Salawu Ajani ati Joseph Ajao Dọkita se bẹbẹ lọjọ na, bakanna ni Ẹgbẹ Ogbomọṣọ Parapọ ti ilu yi ati Ẹgbẹ Ọbanisọla Ẹgbẹ Iya ọmọ na si yọ ayọ alakọbi na lọjọ na.

Sẹlia Awẹro iyale iyawo na ṣe bẹbẹ lọjọ na, o fi aṣọ dabira fun iyawo rẹ abiyamọ na, on paapa si lo awọn aṣọ atata Gbogbo rẹ ndun yungba yungba lọjọna.

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni Yesufu Adisa, T. A. Gbenjo, Raji Ibiyẹmi, Bakare Akanni, K. A. Olode ati Job O. Falade Aṣoju Iwe Irohin Yoruba, Safuratu Abẹni, Aṣiawu Anikẹ ati Falilatu. Ki Oluwa se ọmọ na ni olori ire ki O si fi ire kari o.

## *Ikomo Ladejobi Dun To*

GOMBE-Ni ọjọ Bọ ti iṣe ọjọ kẹrin oṣu keji ọdun yi ni Ọlọrun fi ọmọkunrin gidigbagidigba kan ta Ọgbẹni Ladejọbi Oyekale ati Iyaafin rẹ lọrẹ, nwọn si ko ọmọ na jade ni ọjọ kọkanla oṣu na, Alamojuto, Ijọ Pastor T. Ola. Tanimọwo lo ṣe 'sin isọmọloruko na. Ki nwọn to ṣe Ore ọfẹ ni baba ọmọ na ti pese akara aladun pẹlu obi funfun lati ọna Iṣagamu si ori tabili.

Nigbati o di dede agogo mejila ọsan ni ẹsẹ gbogbo awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ti pe ṣọṣọ. Baba ọmọ na si fi orisirisi onjẹ adidun ati ọti orisirisi tẹ gbogbo wọn lọrun, awọn Ọgbẹni Tafa Arẹmu, E.A.

Laleyọ se gudugudu meje lọjọ na

Diẹ ti aye wa fun lati daruko ninu awọn alabaṣẹyẹ ọjọ na ni awọn Ọgbẹni E. A. Olla [Aṣoju Iwe Irohin Yorub ], D. A. Dare, T. Oyelade, I. Aderinto, E. Ayanṣina, D. Abegunrin, ati E. Egunṣọla. Oluwa ki ṣe ọmọ na ni olori ire, ki O si fi ire kari o.

## *Tani Yio Gbe Jakobu Dide*

Lati oju ewe kẹta

Ṣugbọn iṣe wọn wu mi pupọ gẹgẹ bi oruko wọn. Yiyẹ ni yẹ Ẹiyẹle, riro ni rọ Adaba lọrun, ki iṣe alaikoyẹ ọmọ Adiẹ, yiyẹ ni yẹ ọmọ Pẹpẹiyẹ. Ki Ọlọrun OLODUMARE ati ODUDUWA o ma ṣai jẹ ki o yẹ ẹnyin Ẹgbẹ Afẹnifẹrere (Action Group) nilẹ Yoruba.

Ọlọla Ọbafẹmi Awolọwọ olori ẹgbẹ, ẹmi rẹ yio gun, igba rẹ yio si dara jale. Ma se foiya, iwọ ṣa duro bi Mose ti ṣe ko awọn ọmọ Israeli la Okun Pupa ja ni ijọsi. Awọn ọta ko ni ri nyin gbeṣe o, ipa ọta ko ni ka nyin o. Nitori awọn to wa pẹlu nyin ju awọn to wa pẹlu wọn lọ.

Mo dupẹ fun aye ti ẹ gba mi yi, ọwọ nyin a ma a roke o, oju ko feraku.

KO NI JEKI AWỌ ARA ỌMỌ ỌWỌ NI ISAKA



KO NI JẸKI ARA RẸ RI WURUWURU TABI NI EGBO

"Mentholatum" a ma mu awọ ọmọ ọwọ dan, a si ma a fun un ni alafia. O rọrun pupọ lati lo. Bi o ba ti wẹ ọmọ ọwọ tan, sa rọra fi pa ni ara ati ẹsẹ. Nipa bayi egbo tabi ekuru ko ni le de ara ọmọ na. Gbogbo ara rẹ yio ma a dan borọborọ ni. Gbogbo ọmọ ọwọ fẹran atura ti "Mentholatum" nmu wa. Tete sare lọ ra ide tabi agolo rẹ kan loni. Inkankan ko dara ju u lọ fun pipara.

SA FI PA A

Bere Fun Mentholatum



O wa ninu agolo ati ide.
Eyi ti o jẹ pe awọn The "Mentholatum" Co. Ltd. (Est. 1889) Slough, England lo se gun an.

MENTHOLATUM

Printed & Published by the Amalgamated Press Ltd
5/7 Apongbon Street, Lagos.